# Medicaid àti Ìtọ́jú Lẹ́yìn Ìbímọ Àfikún Ìlera Ọmọdé ni A Fàgùn láti Ọjọ́ 60 sí Ọdún Kan

**Láti Ọjọ́ 1 Oṣù Kẹ̀ẹ̀ta, Ọdún 2023, àwọn aláboyún àti àwọn ọmọdé tí ń gba owó àpawọlé tó kéré jù tó sì lóyún ni a ń forúkọ wọn sílẹ̀ nínú yálà Medicaid àti/tàbí Àfikún Ìlera Ọmọdé ni yóò yẹ láti gbà tó oṣù méjìlá ìtọ́jú lẹ́yìn Ìbímọ báyìí, èyí kò níṣe pẹ̀lú ipò ìwé ìgbélùú tàbí bí oyún náà ti parí.**

## Ohun tí èyí túmọ̀ sí

- Medicaid àti/tàbí Ìtọ́jú Lẹ́yìn Ìbímọ Àfikún Ìlera Ọmọdé ni a ó fà gùn báyìí fún oṣù méjìlá lẹ́yìn oyún èyí kò níṣe pẹ̀lú èyíkéyìí àyípadà tó dé sí owó àpawọlé tí ẹni náà tàbí iye ènìyàn nínú ẹbí náà ní àkókò náà èyí tó le mú kí wọ́n má yẹ fún àwọn ànfàní wọ̀nyí.
- Àwọn Iṣẹ́ tí Medicaid àti/tàbí Àfikún Ìlera Ọmọdé yóò fúnni fún oṣù 12 pẹ̀lú gbogbo abala Medicaid àti/tàbí àwọn ànfàní Àfikún Ìlera Ọmọdé, èyí tó bẹ̀rẹ̀ láti àbẹ̀wò dókítà sí àwọn àbẹ̀wò ilé-ìwòsàn, àwọn ògùn tí a yàn, àti ohun gbogbo tó wà láàrín, èyí pẹ̀lú ìtọ́jú ọpọlọ fún àpẹrẹ.

## Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ

- Ìjọba àpapọ̀ ṣàgbéjáde òfin tuntun kan ní ọdún 2021 gẹ́gẹ́ bí ara Òfin Ìgbanisílẹ̀ ti Amẹrika, èyítí ó fa ìtọ́jú lẹ́yìn ìbímọ síwájú láti ọgọ́ta ọjọ́ sí oṣù 12 lẹ́yìn ìbímọ fún èyíkéyìí ìpínlẹ̀ tó fẹ́ láti ṣàmúlò irú àṣàyàn bẹ́ẹ̀. Ìpínlẹ̀ New York ti ṣàmúlò òfin náà ó sì jẹ́ ìpínlẹ̀ 35 tí a fọwọ́sí fún ìtọ́jú tí a fà gùn.
- Ìpínu New York láti ṣàmúlò àṣàyàn ìjọba àpapọ̀ láti fa ìtọ́jú lẹ́yìn ìbímọ gun tún faramọ́ ètò Ìṣe Ìtọ́jú Ìbímọ ti ìjọba Biden láti ṣàmúgbòrò ìlera ìbímọ, pàápàá jùlọ ní àwọn agbègbè tó nílò ìrànlọ́wọ́. Ìlépa pató ti fífàgùn yìí nínú ìtọ́jú ni láti dín ìwà àìdọ́gba ẹlẹ́yàmẹ̀yà kù èyí tó níṣe pẹ̀lú àrùn àti ikú nípa pípèsè fún awọn ará New York tí kò ní ìrànwọ́ pẹ̀lú ìtọ́jú ìlera pupọ̀ fún ọdún kan lẹ́yìn tí wọ́n bímọ bí wọ́n ti nílò rẹ̀.
- Gẹ́gẹ́ bí ara àṣeyọrí àgbàwí ti NYIC Coverage4All ìpolóngo àti ìgbésẹ̀ pàtàkì láti ráyèsí ìtọ́jú ìlera fún gbogbo olùgbé New York, Ètò Ìṣúná Owó ti Ìpínlẹ̀ New York 2023 ní àfikún pẹ̀lú ìpèsè kan láti fa ìtọ́jú lẹ́yìn ìbímọ gùn láti tọ́jú gbogbo aláboyún àti ọmọdé tí owó àpawọlé rẹ̀ kéré tó sì lóyún, èyí kò níṣe pẹ̀lú ipò ìwé ìgbélùú, tó yẹ fún àmúyẹ owó àpawọlé lábẹ́ Medicaid àti Àfikún Ìlera Ọmọdé.

## Àmúyẹ

- Àwọn tó yẹ fún ànfàní yìí pẹ̀lú gbogbo ènìyàn tó, nígbàtí ó lóyún, yẹ fún ó sì ń gba àwọn iṣẹ́ lábẹ́ ètò Medicaid ti Ìpínlẹ̀ New York tàbí ètò Àfikún Ìlera Ọmọdé ti Ìpínlẹ̀ New York le gba àwọn ànfàní wọnyí. Gẹ́gẹ́ bíi Ètò Ìṣúná Owó ti Ìpínlẹ̀ ní Ọdún 2024, ànfàní yìí ni a ó tún fagùn sí àwọn ènìyàn lábẹ́ Ètò Pàtàkì.
- Àwọn ènìyàn yóò yẹ títí àkókò oyùn náà (èyí pẹ̀lú èyíkéyìí àkókò àmúyẹ látẹ̀yìnwá), kódà tí oyún náà bá wálẹ̀, àti àkókò lẹ́yìn ìbímọ ti oṣù 12.
- Àkókò lẹ́yìn ìbímọ ti oṣù 12 náà yóò bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ tó gbẹ̀yìn oyún náà yóò sì parí ní ọjọ́ tó gbẹ̀yìn ti oṣù 12 náà.
- Bótilẹ̀ jẹ́ wípé ìtọ́jú Medicaid náà ni a ó fàgùn èyí tí kò níṣe pẹ̀lú èyíkéyìí àyípadà sí owó àpawọlé ti ẹni náà tabí iye ènìyàn nínú ẹbí náà ní àkókò náà, àmúyẹ náà ni a le múdópin ní àkókò náà nítorí àwọn nkan wọnyí:
  (1) tí ẹni náà bá fúnra rẹ̀ wípé kí a yọ òhun kúrò nínú ètò náà;
  (2) tí ẹni náà bá kó kúrò ní ìpínlẹ̀ náà;
  (3) tí a bá pinnu àmúyẹ ẹni náà ní ọ̀nà àìtọ́ ní àkókò àtitún pinnu àìpé náà tàbí tí a bá pinnu àmúyẹ náà ní àṣìṣe tàbí ọ̀nà èrú, àṣìlò tàbí iró, àti
  (4) tí ẹni náà bá kú.





## Ìforúkọsílẹ̀

Ìforúkọsílẹ̀ nínú Medicaid àti/tàbí Àfikún Ìlera Ọmọdé ni a le ṣe nígbàkugbà láàrín ọdún.

Bí o ti le ṣàkọsílẹ̀:

- Lórí ayélujára ní nystateofhealth.ny.gov. Ọ̀nà ìtàkùrọ̀sọ kan wà nílẹ̀ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ní àkókò ibi iṣẹ́ oníbàárà láti ràn ọ́ lọ́wọ́ ṣe ìparí ìwé ìbèrè rẹ.
- Pe Ibi Iṣẹ́ Oníbàárà Ìlera ti Ìpínlẹ̀ NY sórí 1-855-355-5777.
- Gba iránlọ́wọ́ ṣíṣe àkọsílẹ̀ ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Olùtọ́ni kan, lójúkojú tàbí nípasẹ̀ ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀. Wá Olùtọ́ni kan ní info.nystateofhealth.ny.gov/ipanavigatorsitelocations.
- Wá àlàyé ni oríṣìí èdè nípa ìtọ́jú ìlera ní info.nystateofhealth.ny.gov/InformationalMaterials

- Àwọn olùgbé Ìlú New York: pe 311, àtẹ̀jíṣẹ́ “CoveredNYC” sí 877-877, tàbí ṣàbẹ̀wò sí on.nyc.gov/healthinsurance fún ìrànlọ́wọ́ àti àfikún àwọn ohun àmúlò.



- Tí o bá wà lábẹ́ ìtọ́jú alágbàtọ́ tàbí àgbàtọ́jú ọ̀dọ̀ tí o kò sì yẹ láti forúkọ sílẹ̀ níbi Ìpatẹ Ìlera ti Ìpínlẹ̀ New York, o tún le ṣàkọsílẹ̀ níbi Ẹka Iṣẹ́ Ìgbàlódé ti agbègbè rẹ (health.ny.gov/health_care/medicaid/ldss.htm)